# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

Ijo 597 TUESDAY MAY 5th 1964 (2D)


## Awon Olopa Ri Ori Enia Ninu Ile Okunrin Kan

IKEJA:- Ni ojo Eti ti ise ojo kini osu yi ni awon olopa mu awon odaran olopa meji kan Phillip Udi, eni ogbon odun ati Simeon Okorie, eni odun mejidinlogbon ti nwon ti nsise olopa nigbakanri wa siwaju adajo Agba Ile ejo kekere Ikeja fun esun owo chin ati riba.

Olopa ti o ba awon odaran olopa mejeji na sejo se alaye fun ile ejo pe, ise olopa ni awon mejeji ti nse, lenu-loloyi ni awon olopa lo si ile okunrin kan, Okwuma, ni Ajegunle Apapa.

Nigbati nwon de inu ile okunrin na nwon ba agbari enia kan n i n u ile okunrin na, o tun se alaye pe, nwon ko lati mu okunrin n a, nwon si so fun un pe ki o mu adota ponun wa (£50) ki awon ma ba se m u lo si Tesan.

Ni okunrin na ba tele lo so fun awon Olopanu. Awon Olopanu lo w a fi ogbon ayinike mu awon olopa mejeji na, ti nwon fe gba owo chin. Adajo ti ye gbi gbo ejo na si oju iwaju, o si gba oniduro enikokan won l o r i ogorun ponun (£100) ati onigbowo lori i y e owo kanna. Bi nwon ba ti pari ejo na si,e o ma a gbo o.

**Adebiyi So Pe:**

# AGBEJORO AWOLOWO HU'WA ARIFIN SI ADAJO

EKO:— Gbegede gbina n waju adajo Agba fun gbogbo awon adajo, Olola Adetokunbo Ademola nigbati Ogbeni 'Duro Adebiyi, abanirojo pataki fun Apapo Ijoba Naijiria so ni ile ejo na ni kutukutu owuro ana wipe 'Awon ojogbon Oloye Amofin ti Oloye Obafemi Awolowo pe wa si Naijiria lati wa gbenuse fun un huwa arufin si Ile ejo giga julo fun orile-ede Naijiria"

Ogbeni Adebiyi so sako niwaju adajo pe "Iwa arifin ni, lati ri wipe, awon Oyinbo Alawo funfun tun nso fun adajo wa pe "adajo si ara re lona o k o j a iwontunwonsi nigbati o nje wipe ile Naijiria ti gba ominira ti a ko si si ni abe Oyinbo Geesi mo.

O tun se alaye pe iwa ti awon Oyinbo na hu si ile ejo ki ise eyiti on gegebi agbejoro Ijoba ko gbodo fi oju fo da ki on ma si mu enu ba oro na, ki on si pe akiyesi awon adajo si oro na.

Sugbon bi Ogbeni Adebiyi ti nso oro yi lo, adajo Agba Olola Veha Bairmain ko je ki o so oro na tan ti o fi gba mo lenu.

Veha: ' Ma a ba oro re lo lori ejo ti o wa niwaju re, mase mo enu kan oro arifin, oro arifin ko lo wa niwaju wa."

Adebiyi: Mo dupe pupo lowo re Olu-a mi, mo kan pe akiyesi nyin si oro na ni."

Lehin eyi ni Ogbeni Adebiyi wa beresi se alaye lori awon eleri ti Ijoba pe lati wa jeri nile ejo.

Ogbeni Adebiyi wa beresi se alaye lori awon eleri ti Ijoba pe lati wa jeri nile ejo.

Ogbeni Adebiyi se alaye pe, Ogbeni Henry Olcari ati Anthony Oboh ye lati jeri fun ile ejo. O tun se alaye pe adajo Ile ejo ti o se ejo na tele ti yiri ejo na wo daada ki o to pe awon eleri na pe ki nwon o wa jeri fun Ile ejo.

O tun se alaye pe, ejo ti awon agbejoro awon olujejo nse sile pe nwon ko ye lati jeri ki ise be rara.

Adetokunbo: "Oro awon eleri ti nwon so pe ko dogba mo ara won nko?"

Adebiyi: "Mo mbo wa so ti iyen lajepe, gbogbo re na ni ngo so."

Opolopo ibere ni awon adajo bere lori oro awon eleri ti o yato si ara won eyiti ogbeni Adebiyi dahun awon ibere na.

Sugbon oniwe irohin ti o mo nipa akiyesi fi ye wa wipe, idahun na ko te awon adajo lorun rara.

Lehin opolopo ibere lori oro yi, Ogbeni Adebiyi so pe Patrick Dokotri, Henry Olcari, Anthony Oboh ati Oloye Richard Babalola ye lati jeri niwaju adajo.

Mbanefo: !!Dokita Oladipo Maja nko?!

Adebiyi: "Eyini igba kini ti e n i k a n tabi enia meji y i o ma a gbimo po ni ikoko lati g b e ogun t i Ijoba"

Adajo Taylor: "N j e adajo le se idajo ewon fun Olujejo nigbati eri awon eleri k o dogba ti o si yato si ara won?"

Adebiyi: "N i n u iwe ofin iselu Naijiria oju e w e etadinlogosan (page 177), eleri kansoso ni ofin fe, ofin ko fe eleri meji ki o to se idajo fun arufin"

Mbanefo, A d a j o agba Ipinle Ila Orun: "Nje ti o b a j e eleri eke nko?.

Adebiyi: Para, ki ise be, sugbon e lo wo oju ewe iwe ejidinlogosan (page 178), a yafi Adajoba fi oju fo ofin yi da."

Lehin eyi, ni Ogbeni Adebiyi tun wa se ala-

Wo Oju Ewe Kefa



Olola Veha
*Adajo Agba*



Oloye Awolowo



Ogbeni 'Duro Adebiyi
*Agbejoro Ijoba*



Olola Ade. Ademola
*Olori Adajo*


## Nje Oke—soro wa fun E Bi?

FUN IWADI OHUNKOHUN KOWE SI WOLI

D. Abiodun,
P. O. Box 1554,
Lagos, Nigeria.

Jowo fi Stampu toro ati address re ran se si wa lati tete da esi pada ni kiakia.

# ỌTẸLẸMUYẸ NKI NYIN O

E ku owurọ o, ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, gbogbo ẹyin ni mo ki patapata porongodo nko ni olodi kan. Mo ki Olotu ati awọn alabaşişẹpọ rẹ pe ẹ ku işẹ, o ọpọlọ ti ẹ fi nşe, ko ni daru mọ yin lori. Ẹnyin[a]şaşọ ko ni şi işọ şa o lagbara Oduduwa. Nko le gbadura fun ẹlomiran, ki nma gbadura fun ara mi o, emi papa ko ni şişe, nko ni şişọ, itẹlẹ mi ko si ni bi ọmọ araiye ninu lagbara Oluwa.

Mo ti şeleri, mo si ti pinnu lati gbogun ti awọn Eyi jẹ-eyiojẹ loni, gẹgẹbi ẹyin papa si ti mọ pe, "Ẹlẹgbẹde ki i lu igi airo" dandandan nti dan ngo şe bẹ ẹ k-ni.

ỌTẸLẸMUYẸ PADE AWỌN EYIJẸ-EYI O JẸ

Bi mo ti nlọ ni adugbo kan ti nwọn npe ni Idi Araba ni mo ba awọn ogunlọgọ Eyijẹ-eyi-ojẹ ti nwọn nti kadi alarabara ta tẹtẹ bi mo ti yọ si wọn fusa ni nwọn ti bẹrẹsi wipe. Ha! irẹ run, ha!! irẹ run!!! itumọ eyi ni pe, abami enia wọ arin wọn.

Mo fi gbigbọ şe ailagb, mo rora sunmọ wọn gẹnnẹ, mo ki nwọn pe, "alafia fun nyin" nwọn si damilohun pe " alafia fun iwọ na.

Mo rora pa agbada mi mora, bi idan ni mo kọja iarawọn nitoripe n..o fẹ igbati igbarun awọn onijibi-ti na. Nko itl rin ju adọta ẹsẹ bata si ibiti wọn gbe ota tẹtẹ na, ni mo gbọ igbe. "Mo ku o! Mo ku o!! oro o!! baba ti nlọ ẹ gba mi o awọn ẹyijẹ eyiojẹ ti gba wo ọwọ mi o nwọn si ti sọ mi di ẹdun [a]rinlẹ"

Mo boju wo ẹhin Bi mo ti wẹhin o di ọdọmọkunrin kan ti o nlagun bẹrẹ wọ o ni o dọbalẹ o si nbẹ mi pe ki nba on kalọ.

Mo wa sọ fun pe, mo gbọ gbogbo ohun ti o wii patapata, kini sun ọ de ib tẹtẹ ṭita ?

IDAHUN

O ni, alagba Oluwa dakun ma fi wa le awọn onijibiti lọwọ, gẹrẹ ti mo gba owo oşu mi tan, ni mo wa lugbadi awọn onijibiti na. Şile kan ni mo kọkọ fi ta ki nto wa jẹ pọnnu kan, eyi ni o wu mi lori pe ti mo ba kuku fi pọnnu kan ta ngo jẹ owo gọbọi. Lotitọ nkọ o, bi ere bi awada ni mo ba jẹ pọnnu mẹwa.

Mo fo soke mo bẹrẹ si yọ, şẹşẹ bi ọra yabọ, a şe mo şi mbọ wa sun ẹkun. Bi mo ti yẹhin pada, ki nma lọ, ni ọkan ninu awọn onijibiti na ba gba mi ni iyanju pe, ti n e ba tun fi pọnnu mẹwa ọwọ mi ta, ngo jẹ ọgọrun punnn, ara mi ba wọ aşọ ni mo ba ko ogun pọnun ti mo ni l'aiye l'ọrun fi ta.

Ko ṭẹ lẹhin a ni nwọn bẹrẹsi şa mi raninranin, lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ba tuka mọ mi ri ibi tẹ ninu wọn, nşe ni mo lọ mọ, ti mo si bẹrẹsi kigbe, nigbati awọn ẹlẹgbẹ rẹ ri i pe nko jawọ lara rẹ ni nwọn ba fi şe alugba ni a nlu toto. Ni kukuru ni owo mi ba gun ni mo tun jiya [a]gbe.

Ohun ti o wa buru ju nibẹ ni pe, ko si owo lọwọ mi mọ ti ngo fi jẹun di ipari oşu" Lailai aiye mi nko ni san aşọ bẹ ẹ şoro mọ

IBOSI ỌLỌPA

Emi Ọtẹlẹmuyẹ fi ọrọ ọkunrin yi kẹwa kesi

Wo Oju Ewe Karun

## Bi Ori Ba Pẹ Ni'lẹ A Dire

YABA:— Irohin ko to afẹjuba [a]bi bi ayẹyẹ eto inawo ti isin igbeyawo ti emidan Esther Johnson ati ẹgbẹni Joshna Ayẹni, şe ni ọjọ ẹjọ bọ ti işe ọjọ kẹtalelogun osu ti o kọja yi, ninu ile Ọlọrun, St. Dominic Church Yaba.



Irohin fi iye wa pe ẹsẹ gbogbo awọn igbajumọ ati sanmọri ilu lo pe sibi ayẹyẹ eto igbeyawo na ni ọjọ na. Ọgbẹni Joshan Ayẹni jẹ ọga agba awọn ọlọpa ti o fi fi işẹ ọlọpa silẹ ti o si nşe işẹ owo nisisiyi larin ilu Eko.

Oniwe Irohin wa Ejongboro ta wa lolobo pe, Esther Johnson ti o nşe igbeyawo yi ni o pa ọkọ rẹ, ọgbẹni Maurice Hall, oyinbo ti o nşişẹ ninu ọgba ọkọ reluwe ninu ọdun 1952.

Nigbati nwọn şe ẹjọ rẹ, Johnson wa ninu ọyun nwọn si şe idajọ iku fun un pe ki nwọn lọ yẹ igi fun un Şugbọn lẹhinti o ti lo ọdun diẹ lẹwọn ni Ijọba sọ pe, ki nwọn mọ yẹgi fun un mọ, şugbọn ki o wa ni ẹwọn ọdun gbere, ki o si ku si ọgba ẹwọn.

Nigbati o di ọjọ kini oşu kẹwa ọdun 1961, lẹhinti ti o ti lo ọdun mẹsan lẹwọn ni Gomina Agba fun Apapọ Ijọba Naijiria ba paşẹ pe ki nwọn fi silẹ. Lati igbati o ti jade lẹwọn ni o ti nşişẹ ni Ile iwosan (Orthopaedic Hospital) Igbobi ki o to şe iyawo ninu oşu ti o kọja yi.

Oniwe irohin wa Ejongboro ti lọ ri obinrin na ninu ọsẹ ti o kọja Gbogbo itan igbesiaiye rẹ, bi o ti fẹ oyinbo, ohun ti o da ija silẹ, ti o fi pa ọkọ rẹ oyinbo.

Ati gbogbo awọn okan ti oju rẹ ri ni ọgba ẹwọn ki o to jade ni o sọ fun Ejongboro. Gbogbo itan yi, ni Ejongboro yio bẹrẹsi ma a sọ ni ọsẹ ti mbọ. Tete ra iwe irohin Imọlẹ ọrọ pọ nibẹ.

# Ogun Ọrun Dide Si Ọgun Aiye NWọn Mbara Wọnja

Lati Ọwọ Ẹsọ. AJEGUNLẸ

Bi itan na tiṣe bẹrẹ niyi. Ọrun ati Ilẹ jijọ nlo ni oko, nwọn nna ẹsẹ lọ. bẹni nwọn ṣe koogẹ eku ẹmọ kan, nwọn lupa, nwọn si mu dani, lọ sibiti nwọn nlọ. Tẹlẹ-tẹle ọrun ko jina si ilẹ lakoko na on ni nwọn npe si Igba-nla-meji to sojude ara wọn awọn mejeji a ma baara wọnjiroro.

Ko si ohun ti o mbẹ laiye ti ko si ni ọrun, nkan ti nwọn ba nṣe laiye dandan ni ki nwọn ṣe ni ọrun Ayani, o gbọ bi awọn Onigbagbọ ti nwi pe, bi a ti nṣe laye, bẹni nwọn nṣe ni ọrun.

To! nigbati Ọrun ati Ilẹ de ibiti nwọn nlọ nwọn fi imọ ṣọkan wipe, ki nwọn pin Eku Ẹmọ ti nwọn pa,

Nwọn si pin Eku Ẹmọ na. Ọrun bẹrẹ, o gbe ori Ẹmọ na, Ilẹ du mọ lọwọ wipe bawo ni Ọrun ti ṣe ni lati gbe ori Eku na, Ibẹ ni Ọrun ba fi itan balẹ wipe Agba lo nyọ ọgbọ ọran, On ni agba, nitoripe ẹniti a ba ni aba, ni a npe ni Baba On Ọrun ni Olodumare kọkọ ṣe ẹda nṣe ni ilẹ wa ba on laiye.

Ilẹ binu patapata, o fi le ogun, Ọrun fi le ọgbọn o ni Ọrun ko ni gbe ori Eku Ẹmọ na. gbogbo nkan ti o ba gba ni awọn yio fi fun loni, Bi o le dogun ko dogun bo si le dija ko dija

Bi o si le dija ko di ibinu, ojo pa eve koko, bo le ya ko ya.

Nigbana ni Ọrun dahun wipe, o ṣe ọrọ eriwọ ki baba lọ wipe, o dọwọ ọmọ on ni ọrun, Bi o ba kan ọrọ ti kiniun yio fi ṣe akapo fun ẹkun, ọlọdẹ ni yio fi ọwọ mu ọdẹ rẹ. Bẹni Ọrun ta ilẹ nipa, o si kun lọ si sanmọ ni biti awọn ara inu ilẹ ko ni le de.

Ayani, o gbọ bi sọlomọn ọba ti wi, o ni ko si ẹniti o goke lọ si ọrun ri tabi ti o ti ọrun sọkalẹ, oju koti ri bẹni eti koiti gbọ finrin.

Nigbati ọrun fo lọ bayi lẹsẹ kanna ọsan di oru awọn Irawọ ko fi imọlẹ rẹ han, orun kọ ko la, Ilẹ gbidanwo lati lọ ba Ọrun nibiti o gbe wa, o sọ ara rẹ si oke Ayani, o ri i, eyi lo jẹki a ma ri awọn oke nlanla lori ilẹ.

'Omi ṣe iranlọwọ fun ilẹ ofo lọ si oju sanmọ ṣugbọn o tun pada wa silẹ.

Awọn agbado taku pe, awọn ko ni gbo, isu kọ ko ta, ina kọ ko jo, bayi ni ọtẹ wa laiye, o si wa lọrun idarudapọ gba ile aiye kan ọrun ko sunwọn gbo—gbo aiye ṣokunkun biribiri, idamu gba aiye ati ọrun kan Ọrun kọ lati pada wa silẹ, bẹni ilẹ kọ lati sijada fun.

Li ọjọ kan awọn ọdẹ aiye ko ara wọn jọ lati lọ ba Olodumare nipa inira ti o ba araiye yi nwọn fẹ mọ ki ni araiye ṣe ti orun ko yọ mọ, ti osupa ko han, ti nwọn gbin agbado ti ko gbo ti isu ko ta

Nigbati awọn ọdọ aiye de ẹnu ala aiye ati ọrun, nwọn ṣe kongẹ awọn ọdẹ ọrun ti awọn na mbọ wa si ile aiye lati mọ kini ẹṣẹ ti ara ọrun ṣe ti nwọn ko fi ri ẹbọ tabi etutu jẹ.

Awọn ọdẹ ọrun pagọ, nwọn tẹdo si ẹnu ala ọrun bẹni awọn ọdẹ aiye ṣe pẹlu Koiti pari.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 2[illegible]-Feb. 19) Ọjọ oni dara fun obinrin adelebọ lati fi awọn ohun ọsọ titun sinu ile, orire ni ọjọ oni jẹ fun obinrin abilekọ.

PISCES (Feb. 20-March 20) Iwọ yio gbayi larin ẹgbẹ loni awọn ọrẹ ati ojulumọ nwoju rẹ fun iranlọwọ owo ati onjẹ

ARIES (Mar 21-April 20) Jẹki ẹniti oloye lori se amọna rẹ, ki o fi oye han ọ, ki o to di wipe o nọwọ mu iṣẹ miran ṣe ni ọwọ owurọ yi.

TAURUS (April 21-May 21) Ọja ti o ba ta tabi ti o ra loni yio ni ere lori Ọna kan lati fi wa owo ni eyi jẹ.

GEMINI (May 22-June 21) Iṣẹ kan ti o ṣeṣẹ da nfẹ atunyewo daradara, ṣugbọn o to ki a fun ọ ni ere.

CANCER (June 22-July 23) Ọjọ to lere lori ni oni yi jẹ maṣe duro, ṣugbọn ki o ma tẹ siwaju ninu eto atun ṣe

LEO (July 24-Aug 22) Oni dara fun ọ, iwọ yio ri owo gbamu loni, owo yio si ba ọ jẹ fun lilo

VIRGO (Aug 24 Sept 23) Iwọ yio ṣe iṣẹ rẹ yanju kedere lasi iye meji, iṣẹ rẹ yio si yanju.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Iwọ yio gbọ irohin agbayanu kan, iwọ yio si lọ kesi ọkan ninu awọn ọrẹ rẹ

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Majafara tete lọ san gbese lori ọja kan ti o ti lọ ra, gbese ko dara lọrun

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 22) Tete bẹrẹ lori ọrọ iṣẹ kan ti o mbẹ nilẹ, bi oko ba tete yanju rẹ, ọna le di

CAPRICORN (Dec 23-Jan 20) Ohun kan ti o nwa ọwọ rẹ yio tẹ inu rẹ yio dun de gongo


# Iboosi Ikọ Ti Ọjọ Rẹ Ti Pẹ Lara

Pupọ ninu awọn egbogi rọbirọbi ti wọn npolowo ti wọn si nta kakiri igboro ilu Eko ati ni igberiko ko ni ṣe iwosan wọn lailai afi ki ori oulowo haunhaun atamase egbogi ti o lagbara gidigidi ti o le ṣe iwosan rẹ titi de inu ifun ati igb-aya ti yio mu ọ ma tu "Ikọ" mọ bi kẹlẹtẹ jade ti o ba rhu ẹ titi yio fi tan ni inu rẹ patapata. Awọn ikọ miran wa ti o dabi ẹnipe wọn ama la ogun labi orisirisi egbogi tabi ti o ba jẹ pe bẹni, agba ọ ni imọran wipe ki o ma lo egbogi awọn ara ilu Abyssinia ti nwọn npe ni "Etibard" pẹlu egbogi ti o ba amu

PORAL TABLETS
THIOLYPTINE SYRUP
THYMO-EPHDRIN LINITUSS
ETIBARD ABYSSINIA POWDER

Fun iwosan ikọ Asima, ikọ fere ikọ otutu igba-aiya ikọ gbẹdu, ikọ-ọnafun, ikọ-gbigbẹ tabi eyiti o ma nmu ki enia ma ha ọna-ọfun tabi pẹlu kẹlẹbẹ tabi ti o ma njẹ ki nia ru nipa wahala tabi aikoni le sun daradara lọsana ati loru-gbiyanu lati dan ọkan ninu awọn egbogi alagbara idigidi wọnyi wo fun ara rẹ iwọ yio si ri iyatọ gburugburu larin wọn si awọn olomi ṣorokiti ti wọn nta kakiri

O daju mbẹ iwọ yio bẹrẹ si ri alafia, iwọ yio ma ẹun daradara wasi ma sun fọnfọn pẹlu Alafia de si ọ ni yẹn

Bere egbogi ajebina yi ni ṣọbu awọn:—

Waterloo Medicine Store
8 Plamchurch Street, Lagos
Phone:-22878 ,Nigeria, (Ọja ita Faji)
NIGERIA MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos

# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Ti Nbọ Bi?

"ALAMU LABEKA ALAMU LABEKA"
MO JẸ KI O, OLUWA MO JẸ IPE RẸ
ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe
"AFINIMONA NPA ISIN HAJI"
LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INAKUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa ọwọ se Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Olubor gbogbo ẹda patapata" Amin

WAS SALAM"

AKIYESI Gbogbo Musulumi Ododo [illegible] oyẹ ki o ri Ana lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA

*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan

# Opin Ohun Gbogbo Sun-mọle

Lati ọwọ SAMSON ỌLALERE ỌLAYANJU

Ẹyin ọmọ enia ẹjẹki a dupẹ lọwọ Ọlọrun ti o jẹ ki a jẹ alabapin ninu ogun awọn enia mimọ nipa ọreọfẹ Jesu Kristi Kolose 1 : 12. Ẹnyin onigbagbọ agbaiye ẹ jẹ ki a ro igbẹhin wa ati igbesi aiye wa wo daa da lati ibẹrẹ titi de opin, nitoripe igbẹhin ni alayo ta. Bi a ba le gbe adọrin ọdun laiye kini alero pe ale rigba lọwọ Ọlọrun gẹgẹbi ere isẹ wa labẹ ọrun. Rere ni tabi buburu ni yio jẹ ere wa.

Mo fẹ ki ẹ mọ pe gbogbo wa ni a o farahan niwaju itẹ idajọ Kristi. Ẹnyin ọmọ enia iku ko da ọjọ bẹni arun ko da oṣu fun ẹnikẹni, iṣẹ ti o ba nṣe ati iwa rere ti o ba nhu ni a o fi dajọ fun ọ Ki a maṣe tan nyin jẹ ohunkohun ti enia ba funrugbin ni yio ka Galatia 6 : 7

Awọn ọrọ kan wa laiye loni ti o ba ọrọ Ọlọrun jẹ ni ọkan wa ti o si nfun ọrọ Ọlọrun l ọ r u n ni ọkan ọmọ enia awọn na ni ekini Ainisẹlọwọ e k e j i Ailowo lọwọ a t i ẹkẹta Airọmọbi ati awọn nkan bẹẹbẹ lo

Bẹni awọn nkan wọnyi ko pe ki a mọ sin Ọlọrun Alaye, bi a ba sin Ọlọrun ni a to le ni awọn nkan ti a nfẹ pẹlu. Matt. 6:33. Awọn miran ni awọn sin Ọlọrun titi awọn ko ri oju tu rẹ, iru bayi ni iwe Ifihan 3 : 15 npe ni ko gbona ko tutu.

Ti a ba se akiyesi ẹgbẹ onigbagbọ k a n to njẹ "World Christian" eru saders Association ẹorukọ Olori wọn ni Woli Adetoro ni alalẹ ni nwọn ma nṣe iwasu ita gbangba Bi oba ni o nfẹ nkan lodọ Ọlọrun lọgan ni ori gba.

Awọn ọmọ araiye ko fẹ sin Ọlọrun mọ, iwe mimọ Ọlọrun sọ pe ẹnikẹni ti o ba kọ ti ko sin Ọlọrun yio jẹ iya, bẹni Kurani suratu ayat 55 sọ pẹlu Neberu 13 : 5 ako mu ohunkohun wa saiye bẹni a ni mu nkankan pada lọ. Ẹma jẹki ati tori ohun padanu ẹmi wa. Timothy 6 : 7

Oluwa ko fẹ ki ẹnikankan segbe, Oluwa tun pe awọn ọlọrọ si ironupiwada I Timothy 6 : 17 o yẹ ki gbogbo wa gbẹkele Ọlọrun ki a mọ gbẹkẹle ọrọ aidaniloju. Ọlọrun ko fẹ ki a segbe n i n u ẹsẹ wa II Peteru 3 : 9

Ni ọjọ ikẹhin nigbati Oluwa ba nko awọn olotitọ jọ ki Oluwa ka wa mọ wọn ni ọjọ na, ki a le fi ijọba Ọrun se ere jẹ amin

---

Lati Oju Ewe Karun

Ọlọpa pe, ki nwọn tete kọ ibi ara si ọrọ awọn onijibiti wọnyi lati le ti wọn siuu idẹkun Ijọba, ki pasan ijọba ba le ba wọn lara

Ẹtunse akiyesi Ọlọpa, awọn ibudo ile iṣẹ Ẹyiiẹ eyi o jẹ na ni ọna Igbobi-College, Idi Araba, titi Ikorodu, Ọna Apapa Ẹiẹmu ati awọn abule kee kee ke ti o wa ni agbegbe Apapa.

Inu mi yio dun ti ọlọpa ba tete mojuto ọrọ na, ki awọn onijibiti yi ba le dekun iwe aidara na kiakia.

IKILỌ

Ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ, ẹ gba imọran yi ki ẹ si muṣẹ eyi ni yio gba yin silẹ lọwọ idẹkun awọn onijibiti ti mo nwi yi.

Ekini ibikibi ti ẹ ba ri awọn onijibiti yi, ẹ pe ọlọpa mu wọn.

Ekeji— Ẹ maṣe duro wo wọn, yala ẹo ba wọn ta tẹtẹ.

Ẹkẹta:— Ẹ ma ranti pe, ọna ọla kan ko si, ju iṣẹ Ogun oju ẹni lọ.

Bi ẹ ba tẹle a w ọ n imọran mi yi, nwọn ko ni ri yin gbese. Ẹniti o ba ni eti lati fi gbọ, ki o gbọ ni ọrọ t'emi Ọtẹlẹmuyẹ.

Emi Ọtẹlẹmuyẹ nrele o, bi Oluwa bo ba kọ iṣẹ eru rẹ, ẹo tun ma a gburo mi ni mushin nitoripe mo fẹ ja lu a w ọ n onimọto t i nwọn nkero lati Mushin lọ si Itirẹ. Ka fi're pade o.

# IWE ITUMỌ ALA

Josẹfu Alala ti ẹ ti nkan ninu iwe Irohin Yoruba ti jade ni odindi fun tita nisisiyi.

OHUN TI O WA NINU IWE NA

1. Egbogi Ajẹbidan agbabiẹtu.
2. Odu Ifa mẹrindinlogun lati ma a fi yẹ itumọ ala rẹ wo.
3. Ẹnikẹni ti o ba ra iwe yi ni anfani lati bere ala rẹ nigba gbogbo lọfẹ lọwọ Josefu Alala.
4. Koiti si ikeji rẹ ninu iwe itumọ ala ti o ti njade ri nitoripe JOSẸFU ALALA ni o ṣe e

Tete ra tirẹ loni ki o to tan.

AKIYESI

A tun nfẹ asoju ti yio ma ba wa ta iwe na. owo pọọku ni ao ta fun wọn ki nwọn ba ri ere gọbọi jẹ ti o ba fẹ se asoju wa kọwe fun iwe adehun,
Iye owo 5/- £2

**J. O. Shoyinka**
N2/99 Shittu Street
Ibadan

tabi
1, Isiba Street Odo Ẹran
c/o Postal Agent
Itirẹ,
Via Suru—Lere,
Yaba


BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANSE TI NWỌN NPE NI- Eleyi yatọ patapata si awọn

**RICHELET**

Rọbi-rọbi. Ẹlẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoroẹbuburu ti o ba wa ninu, ẸJẸ ARA' ti Mọna mọna

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nti kakiri ni owo pọọku adimowọ tabi ki o lọ nilẹ ko di o w o Iyẹn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni lẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ojulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati ti awọn Tatambulu si Itali jẹ

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun. Jẹdijẹdi Akọba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa Egbogi-Amodi Apo ile ilọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa nba ẹjẹ ara rẹ patapata yio si ni ẹjẹ rẹ mọ tonitoni pẹlu.

Ṣa dan igo rẹ kan wo iwọ yio si ma a rohin rẹ fuu ẹlomina pẹlu.

Bere Ṣọbu awọn:—
Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street ( Lagos.
Phone: 22878 Nigeria, Ọja Ita Faji)

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

IROHIN IMỌLẸ

IMỌLE ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 597 TUESDAY, MAY 5, 1964 (2D)

## Ọkọ Oju–Omi Kan Ri Sinu Okun

SICILY:- Idaamu nla ba gbogbo enia nigbati iji nla lile kan de ba awọn ọlọkọ loju omi ti iji na si nbi ọkọ siwa bi si ẹhin, ti ọkọ oju omi kan ti awọn awọn ero mejidinlo un si ri si agbami Okun ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ keji oṣu yi, ni ilu kan ti nwọn npe ni Sicily, ni agbegbe Italy ni Ipinlẹ iwọ Orun Aiye.

Irohin fi ye wa wipe ojo nla kan na o fẹ lọ ni ojo na Nigbati ọjọ na ti mura lati rọ ni o ti bẹrẹsi fẹ atẹgun lile Nigbati awọn enia na si wipe ọwọ atẹgun ba nle, ti o nbi ọkọ oju omi siwa ti a si tun nbi i sẹhin ni nwọn ba nsare lọ si Ebute pe, ki awọn tete lọ gunlẹ.

Ṣugbọn nigbati ọkọ na yio fi sare de Ebute, nibiti yio gbe gunle si ni ọkọ oju- omi na ba sojude larin Okun ti gbogbo awọn enia mejdinlogun ti wọn wa ninu ọkọ na si ṣegbe patapata. Irohin fi ye wa pe awọn Ọlọpa oju omi nwa ibi ti ọkọ oju omi na ri si lati yọ awọn enia inu rẹ jade Atun gbọ wipe nwọn ti nṣe eto lati gbe ọkọ na jade kuro ninu agbami Okun.

# KOSI IJA NINU ẸGBẸ DẸMỌ – FANI

IBADAN:— Oloye Rẹmi Fani-Kayọde, Igbakeji Alakoso Ijọba Ipinle Iwọ Orun Naijiria ati Minista Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ sọ ni Ibadan ninu ọsẹ ti o kọja yi sọ wipe ko si ija tabi edeaiyede larin awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ N. N. D. P. gẹgẹbi awọn kan ti nsọ kakiri kan wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ nitoripe awọn kan fẹ ki Ọba C. D. Akran ti iṣe Minista eto inawo gba ipo ti Oloye Fani-Kayọde wa.



Oloye Fani—Kayọde Igbakeji Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria

Ṣugbọn Oloye Fani Kayọde sọ ni Ibadan ni opin ọsẹ ti o kọja yi pe, ko si ija larin awọn rara.

Oloye Fani–Kayọde tun so wipe ki iṣe otitọ wipe ija tun wa larin on ati Oloye S. L. Akintola, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati Olori ẹgbẹ Dẹmọ.

A gbọ wipe ẹgbẹ Dẹmọ fẹ faramọ ẹgbẹ Olomi ki awọn ẹgbẹ mejeji jijọ ma a ṣepọ, ṣugbọn a gbọ wipe Oloye Fani Kayọde lodi si aṣepọ awọn mejeji na Ni nkan bi ọsẹ diẹ sẹhin ni a gbọ wipe edeaiyede

Ṣugbọn Oloye Fani-Kayọde sọ ni Ibadan pe, ọrọ na ki iṣe otitọ, on paapa nwa aṣepọ ohun gbogbo ti o ba le mu alafia on ifaiyabalẹ wa fun awọn enia Ipinlẹ yi.

Oloye na wa pari ọrọ rẹ pe "Enia ki iri ọkọ nilẹ ki o fi ọwọ ko imi, kini a ko ma a jẹ igbadun fun, ki a si ma a yọtọmi"

## LATI OJU EWE KINI

ye pe, oṣu mẹta ni awọn enia na fe iọ fi kọ iṣẹ ogun ni Ghana ki nwọn to pada de ni ọsẹ kẹta nigbati nwọn gbọ wipe Ijọba ti fi ofin pajawiri gbe Oloye Obafẹmi Awolowọ.

Otun ṣe alaye epe ni Ghana ni awọn enia na wa ti awọn ti ngbọ wipe rogbodiyan ti bẹ silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ọgbẹni Adebiyi tun ṣe alaye siwaju si i ninu ọrọ rẹ pe, ni ọjọ kejilelogun oṣu kẹfa ọdun 1962 ni Ijọba fi ofin pajawiri gbe Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ kuro ni Ikẹnnẹ lọ si Lẹkki.

Ṣugbọn lẹhin eyi ni Ọgbẹni Adebiyi wa mu ẹnu kan ọrọ awọn Ọlọpa wipe, ki iṣe otitọ wipe, pẹlu ipa ni awọn Ọlọpa fi mu awọn enia na rejọ.

Ọgbẹni Adebiyi ṣe alaye pe, ofin ilẹ Naijiria gbooro ju ti Ijọba Gẹẹsi lọ, gẹgẹbi awọn agbẹjọro ti nfi oju wo, o si ṣe alaye pe, a ko le fi ofin mejeji we ara wọn

Ọgbẹni Adebiyi tun ṣe alaye o tun ka akọsile ẹjọ ti awọn ọlọpa ro fun ile ẹjọ pe, nigbati awọn kọkọ lọ si ile Oloye Awolọwọ ni Ikenne, awọn ba Sẹgun Awolọwọ nile ni ọjọ na, awọn ko si ri nkankan ninu ile Oloye Awolọwọ.

Ṣugbọn nigba keji ti awọn lo wa ile Oloye Awolọwọ awọn ko ba Sẹgun Awolọwọ nile, Ijọba ti fi ofin pajawiri gbe Oloye Awolọwọ awọn si ri awọn nkan nja ogun ninu ile rẹ ni ọjọ na.

O wa rọ ile ẹjọ pe on ko ni sọrọ pupọ lori ọrọ na loni ṣugbọn on yio tun mu ẹnu kan ọrọ na ni ọjọ iwaju ki on to pari ọrọ on niwaju adajọ.

Lẹhin eyi ni o wa mu ẹnu kan ọrọ ọgbẹni Cenlman igbakeji ọga ọlọpa ti awọn agbẹjọro sọ wipe ko ni aṣẹ lati gba ọrọ silẹ ni ẹnu awọn Olujẹjọ.

Ọgbẹni Adebiyi gba wipe Ọgbẹni L. Lynn paapa gba wipe Otitọ ni Ọrọ na.

Mbanefo: "Awọn enia na kan ni aṣẹ tabi wa ni aye lati gba Ọrọ silẹ lẹnu awọn Olujẹjọ na bi ? "

Adebiyi: "Oluwa mi, emi na ko mọ bi nwọn ni aṣẹ ati ẹtọ gẹgẹbi iṣẹ wọn lati gba ọrọ silẹ lẹnu awọn olujẹjọ na.

Ọgbẹni Adebiyi ṣe alaye diẹ lori ọrọ na. Ṣugbọn o ṣe alaye pe, on pa ri ọrọ lori gbogbo awọn nkan ti on fẹ sọ lori gbogbo awọn oludajẹjọ, ṣugbọn yio bẹrẹsi ma a soro lori awọn enia kọọkan lati ọla lọ, ṣugbọn lori Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ni on yio ti bere lati ọla lọ.

Adetokunbọ: Nigbawo ni o lero pe o pari ọrọ rẹ? !! Adebiyi; oluwa mi, ọrọ na yio gba mi to ọjọ mẹrin ki nto le pari rẹ mo si lero ọjọ 'Bọ ti iṣe ọjọ keje oṣu yi ni ogo mi ọrọmi de opin.

Ile ẹjọ na pari ijoko wọn ni dede agogo meji ọsan wọn osi tun maa ba ẹjọ na lọ ni owurọ yi.

Oniwe Irohin wa kan fi ye wa pe,awọn ero to lọsi ile ejọ lana pọ ju awọn ti o ti nwọn tẹlẹ lọ, ti o fi je wipe, ọpọlọpọ enia ni awọn Ọlọpa dapada sẹhin nigbati ko si aye mọ ninu ile.

## E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojoojumọ

## AKIYESI PATAKI!

Eyi ni lati kede fun awọn Onkawe IROHIN IMỌLẸ jakejado Ilẹ Naijiria pe OTẸLẸMUYẸ ti ti aio de nisisiyi Ọrọ rẹ yio si ma a jade ninu IROHIN IMỌLẸ deede nisisiyi nitorina ki nwọn onkawe wa mura silẹ lati ma a ka igilango ọrọ OTẸLẸMUYẸ ti yio ma jade ninu Iwe wa na,

OLOTU

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Daugboye Street Lagos Phone 21985
Editor TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga 5/5/64